# OMI, MANNA ATI ÀPARÒ

## Ẹksodu 15:22-27; 16:1- 36

## ẸKỌ 58 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ẹ mã ṣe ohun gbogbo li aisi ikùnsinu ati ijiyan" (Filippi 2:14).**

**Wọn Yara Gbagbe Iṣẹgun**

Nipasẹ Oluwa, awọn Ọmọ Israẹli ti ni iṣẹgun ti o logo lori awọn ara Egipti ti wọn lepa wọn titi de Okun Pupa. Gbogbo awọn ẹṣin ati awọn ẹlẹṣin ni o ti ṣegbe sinu omi, awọn Ọmọ Israẹli si ti fi oju ara wọn ri i bi iṣubu awọn alaiwa-bi-Ọlọrun ti pọ to. Awọn Ọmọ Israẹli ti ṣe ajọyọ iṣẹgun nlá nlà, wọn si ti kọ orin iyin si Olurapada wọn. Ṣugbọn ohun iyanu ni bi wọn ti n yara gbagbe oore Rẹ!

Ọjọ mẹta pere ni o si kọja ti wọn n kọ orin Mose pe: "Tali o dabi iwọ, OLUWA, ninu awọn alagbara?. . . . ologo ni mimọ́, ẹlẹru ni iyin ti nṣe ohun iyanu?. . . . Ninu ãnu rẹ ni iwọ fi ṣe amọ̀na awọn enia na ti iwọ ti rapada: iwọ si nfi agrara rẹ tọ́ wọn lọ si ibujoko mimọ́ rẹ," irẹwẹsi tun ti de ba wọn. Awọn kọ ni o ṣẹṣẹ kọrin pe Ọlọrun ni o mu wọn jade ti o si ṣe ohun iyanu fun wọn? Ki ni ṣe ti wọn kò le gbagbọ́ pe Oun yoo tubọ maa ṣe iṣẹ-iyanu Rẹ fun wọn sibẹ si i? Nitori omi ti wọn ri ko ṣe e mu, wọn ro pe oungbẹ yoo pa wọn kú. Awa ro pe wọn huwa were ni tootọ pe wọn ko gbẹkẹle Ọlọrun; ṣugbọn wo ọpọlọpọ igba ti iru nnkan bẹẹ n ṣẹlẹ si wa. Ọlọrun yoo tú ibukun ọpọlọpọ le wa lori to bẹẹ ti a oo fi ro pe a ki yoo tun ṣe iyemeji si I mọ. Ṣugbọn bi a ko ba ṣọra lati ka Ọrọ Ọlọrun ki a si gbadura pupọ, lọgan ni a o ri i pe ohun ti o le mu ni rẹwẹsi diẹ yoo de, lẹsẹ kan naa a si bẹrẹ si i wo wahala wa, dipo pe ki a gbẹkẹle Ọlọrun.

**Apẹẹrẹ Wa**

Gbogbo itan gẹgẹ bi awọn Ọmọ Israẹli ṣe la ọpọlọpọ iya ati irẹwẹsi kọja ki wọn to di orilẹ-ede nla ni a fi fun wa ninu Bibeli gẹgẹ bi apẹẹrẹ ohun ti o maa n ṣẹlẹ nigba ti awọn eniyan ba mu oju wọn kuro lara Oluwa, ti wọn si n wo wahala wọn. Gẹgẹ bi a ti n ba akọsilẹ nipa wọn lọ pe nigbakugba ti wọn ba gbe igbesi-aye lati wo Ọlọrun, Oun yoo mu ki wọn ṣe rere A si fun wọn ni iṣẹgun lori awọn ọta wọn; ṣugbọn nigba ti wọn ba n ṣe ifẹ inu wọn, ti wọn si sin ọlọrun miiran, ipọnju ti buru jai, lilọ si oko ẹru ati iku paapaa ni o n wá si ori wọn.

**Itọju Ọlọrun**

Iṣoro nla nla ni nigba ti oungbẹ ba n gbẹ aadọjọ ọkẹ eniyan ti ko si si omi ti o dara to ti wọn i ba mu; ṣugbọn a kà ninu ẹkọ wa ti o kẹhin pe Ọlọrun wi pe, "Ẹ má bẹ̀ru, ẹ duro jẹ, ki ẹ si ri igbala OLUWA" Ọlọrun sọ fun Mose pe ki o ge igi kan lulẹ ki o si ju u sinu omi kikoro ni, a oo si mu un dùn. Ko ṣoro fun Ọlọrun lati ṣe ohun ti o tobi to bẹẹ loju wa. Ohun kekere ni wọn jẹ fun Un. Oun n fẹ ki a kà wọn si ohun kekere, bẹẹ gẹgẹ, ki a si jẹ ki Oun ba wa ṣe wọn. O ti sọ fun wa pe ki a kó gbogbo aniyan wa le Oun, nitori Oun n ṣe aniyan wa (1 Peteru 5:7).

**Iwosan nipa Agbara Ọlọrun Nikan**

Nigba ti awọn eniyan naa pa oungbẹ wọn tan, wọn ni itẹlọrun fun igba diẹ. Nihin yii ni Ọlọrun ṣe ileri fun wọn pe bi wọn o ba gbọran si Ọrọ Oun ki wọn si gbe igbesi-aye wọn fun Un, Oun ki yoo jẹ ki eyikeyi ninu awọn arun awọn ara Egipti wa si ara wọn O sọ gbangba bayii pe, "Emi li OLUWA ti o mu ọ lara dá," bakan naa ni o si n wi lọjọ oni. Bi a ba n gbe igbe aye wa lati wu Jesu, ki a sa ke pe E nigba ti a ba n ṣaisan, Oun yoo si wò wá sàn. Ọpọlọpọ eniyan kọ ni o n fẹ gbẹkẹle Ọlọrun ni igba isisiyii fun iwosan ara wọn nigba ti wọn ba n ṣaisan; ṣugbọn inu Ọlọrun ko dun si awọn ọmọ Rẹ lode oni bi wọn ba kuna lati gbẹkẹle E gẹgẹ bi inu Rẹ ko ti dun si awọn Ọmọ Israẹli nigba ti wọn kùn si I.

Nigba ti awọn Ọmọ Israẹli jade kuro ni Egipti, ko si alailokun tabi abirun laaarin wọn (Orin Dafidi 105:37). Iṣẹ iyanu ni eyi jẹ paapaa nitori wọn ti ṣe iṣẹ aṣekara fun ọpọlọpọ ọdun gẹgẹ bi ẹru awọn ara Egipti. Ọlọrun iba si pa wọn mọ ninu ilera pipe yii titi de ilẹ Kenaani bi kò ba ṣe pe wọn dẹṣẹ si I, ṣugbọn a o kọ́ nipa awọn ajakalẹ arun buburu ti o pa ọpọlọpọ ninu wọn nigba ti wọn ṣe aigbọran. Ohun ti o buru ni lati ṣaigbọran si ohùn Ọlọrun.

**Isinmi**

Elimu jẹ ilẹ ẹlẹtu loju laaarin aṣalẹ, nibẹ ni awọn Ọmọ Israẹli si pa agọ si fun bi ọsẹ mẹta, ti wọn si sinmi. O dabi ẹni pe wọn ni ounjẹ ti o to fun wọn lati jẹ titi di akoko yii; ṣugbọn nigba ti wọn mu ọna ajo wọn pọn lati Elimu, wọn bẹrẹ si i maa ṣe laalaa nipa ohun ti wọn o jẹ, wọn si tun bẹrẹ si i kùn si Mose lẹẹkan si i. O yẹ ki wọn ronu gẹgẹ bi Ọlọrun ti gba ọna ara pese fun aini wọn titi di akoko yii, ki wọn si gbẹkẹle E fun eyi ti o ju bẹẹ lọ; ṣugbọn awọn eniyan naa n yara gbagbe awọn ibukun Ọlọrun!

**Fun Ipẹtẹ Lasan**

O to oṣu kan nisisiyii ti wọn ti fi Egipti silẹ nibi ti a ti n fi ilagba nà wọ́n, ti a si ti fi ipá mu wọn lati ṣe ju iṣẹ ti wọn le ṣe lọ. Ni iwọn ọgbọ̀n ọjọ pere, wọn ti gbagbe awọn alailaanu akoni ṣiṣẹ, kiki ikòkò ẹran, ẹgusi ati alubọsa ti wọn n jẹ ni wọn ranti. Wọn mura tan lati jọ̀wọ́ ireti wọn lati ni ilẹ-ini kan ni Kenaani silẹ nitori ohun ti wọn o jẹ! Wọn dabi Esau ẹni ti o ta ogun ibi rẹ nitori ipẹtẹ lasan.

Nigba ti ebi tun n pa awọn Ọmọ Israẹli wọn tun n kùn si Mose -- Ọlọrun si gbọ́ bi wọn ti n ṣe bẹẹ! A ni lati ṣọra ki a ma ṣe kùn si ẹnikẹni ninu awọn ọmọ Ọlọrun, paapaa awọn iranṣẹ Rẹ, nitori nigba ti a ba ṣe bẹẹ, Ọlọrun gan an ni a n kùn ti.

**Ọlọrun ninu Ọwọ̀n**

Aaroni jade lati lọ sọ fun awọn Ọmọ Israẹli pe Ọlọrun ti gbọ́ gbogbo kikùn ti wọn n kùn ati pe yoo ran ounjẹ si wọn lati Ọrun. Gẹrẹ bi o ti n sọrọ, gbogbo wọn bojuwo iha awọsanma naa ti o ti n lọ siwaju wọn ni gbogbo irin-ajo wọn, Ọlọrun si sọrọ lati inu ọwọ̀n awọsanma naa. O sọ fun Mose pe ki o sọ fun awọn eniyan naa pe ni aṣalẹ Oun yoo rán aparo si wọn lati jẹ, ati pe ni owurọ Oun yoo rán ounjẹ si wọn. O sa gbogbo ipá Rẹ̀ lati fi hàn fun awọn eniyan alaigbagbọ́ wọnyii pe Oun ni Ọlọrun Olodumare. Ounjẹ maa de gẹgẹ bi Ọlọrun ti wi pe yoo de.

**Manna**

Manna ti o bọ si ilẹ yatọ si ohunkohun ti a n jẹ. Onisaamu pe e ni "ounjẹ angẹli" (Orin Dafidi 78:26). Nigba ti iri naa ba ká sẹ, yoo kù awọn nnkan funfun kékèké ni ilẹ, o dabi irẹsi tabi tapioka. Wọn le se e, wọn si le lọ ọ di iyẹfun ki wọn si fi ṣe akara. Itọwo rẹ̀ dabi oyin, dajudaju gbogbo ohun rere ti o le ṣanfaani fun ara ni o wà ninu rẹ̀ lati mu ara lokun, nitori ounjẹ yii ni wọn jẹ fun ogoji ọdun. Loroowurọ nigba ti iri ba dá, ilẹ a funfun fun manna, lọna bayii ko tun si ebi mọ́ fun awọn eniyan naa.

Ọlọrun ni Oun yoo wadii awọn eniyan Rẹ̀ wọnyii nipasẹ fifun wọn ni ounjẹ yii, lati wò bi wọn o ba pa Ofin Rẹ̀ mọ́. Ṣugbọn o dabi ẹni pe awọn kan wa ti wọn ti maa n ṣe aigbọran si I nigbakugba ti aye ba ṣi silẹ fun wọn. Ni akọkọ, O sọ fun wọn pe ki wọn ma ṣe kó ju iye ti wọn le jẹ ni ọjọ kan lọ; awọn ẹlomiran jẹ oniwọra boya wọn ko tilẹ gbagbọ́ pe Ọlọrun yoo rán omiran si wọn ni ọjọ ti o tẹle e, nitori naa wọn kó gbogbo eyi ti wọn le kó. Ṣugbọn eyi kò ṣe ire kan fun wọn. Manna naa bajẹ o si yọ idin. Lẹyin eyi ni o wa kan ọjọ ti o ṣaaju ọjọ Isinmi; Ọlọrun si wi fun wọn pe wọn le kó eyi ti yoo to fun ọjọ meji ni ọjọ naa, ko si ni bajẹ Ṣugbọn lẹẹkan si i awọn kan tun ṣaigbọran, wọn si jade lọ ni owurọ ọjọ Isinmi lati lọ kó, nigba ti Ọlọrun ti sọ fun wọn pe ki wọn má ṣe jade -- wọn kò si ri manna.

**Ọjọ Isinmi**

Ọlọrun wi pe Oun dá ọjọ Isinmi nitori eniyan. O mọ pe eniyan ko le fi gbogbo ọjọ ayé rẹ̀ ṣiṣẹ ki o si ni ara lile. O paṣẹ fun un pe ki o sinmi ni ọjọọjọ keje. Lẹyin eyi Ọlọrun paṣẹ bayii "Ranti ọjọ́ isinmi, lati yà a simimọ́" (Eksodu 20:8). Ọjọ Isinmi ti wa nigba isisiyii ni Ọjọ Oluwa, ọjọ kin-in-ni ọsẹ, a si ni lati ranti lati yá a si mimọ́. Wò o bi aye wa i ba ti layọ to bi gbogbo eniyan ba bu ọlá fun Ọlọrun ni ọjọ kin-in-ni ọsẹ.

Manna yii ko ha ta ounjẹ lasan yọ? Fun odindi ogoji ọdun ni manna ti o to fi n wọ̀ silẹ, a fi ni Ọjọ Isinmi, lati bọ́ awọn ogunlọgọ eniyan wọnyii. Idi miiran ti a fi mọ pe ounjẹ iyanu ni ni pe bi o tilẹ jẹ pe kò ṣe fi pamọ di ọjọ keji ki o ma bajẹ (a fi kiki fun ọjọ Isinmi), Ọlọrun sọ fun Mose pe ki o fi ikoko manna kan pamọ́ lati fi hàn fun awọn iran ti o n bọ̀ ohun ti o mu wọn wa laaye nigba ti wọn n rin kiri ninu aginju, bẹẹ ni kò si bajẹ.

**Manna Wa**

Ọrọ Ọlọrun ni manna fun wa, on ni ounjẹ fun ọkan wa. "Enia ki yio wà lãyè nipa akara nikan, bikoṣe nipa gbogbo ọ̀rọ ti o ti ẹnu Ọlọrun jade wá" (Matteu 4:4). A ko le ka Bibeli tó ni ọjọ kan ki o si tó fun wa fun ọsẹ kan tabi oṣu kan. A ni lati maa ka Ọrọ Rẹ̀ ni ojoojumọ ki a si gba "manna" ọ̀tun ni owurọ ọjọ kọọkan. Eyi yoo mu ki a wà ni ilera nipa ti ẹmi, yoo si mu ki a maa dagba si i lati jẹ Onigbagbọ alagbara.

**AWỌN IBEERE**

1. Bawo ni o ti pẹ to ti Israẹli ti wà ni aginju ki wọn to kùn fun omi? Ati ki wọn to kùn fun ounjẹ? Taa ni wọn n kùn si?
2. Ki ni wọn fẹ ṣe?
3. Ki ni ṣe ti ọwọ̀n awọsanma ṣe pataki fun wọn? Sọ idi mẹta.
4. Irú ounjẹ wo ni Ọlọrun rán? Bawo ni o si ti pẹ to?
5. Bawo ni Ọlọrun ṣe wadii awọn eniyan naa nipa ounjẹ yii?
6. Ki ni manna wa?